# IROHIN IMỌLẸ

IMỌLẸ ỌRẸ AIYE. TẸNI GBOGBO LAWA

No 763 THURSDAY AUGUST 6 1964 (2D)


## Ijọba Iwọ Orun Naijiria Tu Ijọba Ibilẹ Mẹta Ka

IBADAN:- Ni Ọjọ karun oṣu yi ni Irohin de ọrọ a lati ile iṣẹ Alakoso eto Ijọba Ibilẹ ti Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria eyiti ẹgbẹ Dẹmo NNDP nṣe akoso rẹ tun tun awọn ile Igbimọ Ijọba ibilẹ mẹta ka ni Ipinlẹ na.

Awọn il Igbimọ ijọba Ibilẹ mẹta ti ijọba ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria tuka na ni Ijọbo ibilẹ ti Iha Gusi Ijẹbu, ijọba ibilẹ ti Ẹgba Owode ati Ijọba ibilẹ ti Ẹgbẹ Ọdẹda,

Irohin tun fi ye wa lati ọwọ oniwe irohin pe on bere idi rẹ ti nwọn fi tu awọn ile Igbimọ Ijọba ibile mẹta na ka l'ọwọ okan ninu awọn ọga ni ile iṣe Alakoso Ijọba ibile ti ipinle Iwo orun o ni nwọn ko sọ idi rẹ ti nwọn fi tu ile igbimọ na ka

Gẹgẹbi iwe kan ti o njade lati ọwọ ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria fi ye wa pe lati ọjọ Abamẹta ti ise ọjọ kini yi ni nwon tu ile Igbimọ Ijọba Ibilẹ mẹta ka

Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ti yan awọn Igbimọ Afun ishọ ti yio ma a ba eto awọn Ijọba Ibilẹ mẹta ka lo bayi.

Nigbati awọn Dẹmo ti gba akoso Ijọba ibilẹ Iwo Oru Naijiria o ti to bi ogbọn awon Ijoba ibilẹ ti Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun ti ntun ka bayi

# AWỌN ENIA IPINLẸ IWỌ ORUN FẸ DIBO SI ILE IGBIMỌ IJỌBA IBILẸ

IBADAN:— Ni ọjọ'Ru ti iṣe ọjọ karun oṣu yi ni irohin de ọrọ wa lati Ibadan pe Ijọba Ipinle Iwọ Orun Naijiria eyiti ẹgbẹ Dẹmọ (NN-DP) nṣe koso rẹ yio ṣe idibo titun si awọn ile Igbimọ Ijọba Ibilẹ jake-jado Ipinlẹ Iwọ Orun. Irohin na tun fi ye wa pe Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria yio ṣe idibo si awọn ile Igbimọ Ijọba Ibilẹ Ipinlẹ Iwọ Orun ninu idaji oṣu kẹsan ọdun yi.



Oloye ỌBAFẸMI AWOLỌWỌ

Alakoso eto Ijọba ibilẹ ti Ijọba ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ati igba keji Alakos Ijọba ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria Oloye Remi Fani Kayọde si tu gbogbo awọn ile igbimọ Ijọba ibilẹ ipinlẹ Iwo orun ka lẹsẹ kẹsẹ ti ẹgbẹ wọn gba akoso Ijọba na,

Nigbati Alakoso eto Ijọba ibilẹ fun Ijọba ipinlẹ Iwo Orun Naijira tun awọn ile igbimọ na ka tan ni nwọn si bere si ni yan ninu awọn ọmọ ẹgbe Dẹmo lati wa gẹgẹbi awọn ti nwọn tu ka na,

Gẹgẹbi irohin ti a ri gbọ lati ọwọ ọkan inu awọn Ọga ni ile iṣẹ Alakoso eto Ijọba Ibilẹ ti Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun ni Ibadan fi ye wa pe asiko ọdun mẹta ti o yẹ ki awọn ile Igbimọ Ijọba Ibilẹ ni Ipinlẹ na lo si ti to ati pe o si ti kọja bayi

Gegeb Irohin ti o iwe Irohin s pe on ri gbọ lati ọmọ ọka ni u awọn ol ri ẹgbẹ Dẹmọ N. N. D. P. ti nṣe akoso Ijoba ipinlẹ Iwọ Orun fi ye wa pe ohun mẹta lo fe ni ki Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun ṣe ṣe eto idibo si ilẹ igbimọ Ijọba Ibilẹ Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria

Oniwe Irohin wa tun fi ye wa pe awọn nkan to ṣe mi ki Ijọba Ipinlẹ Iwọ ornn eyiti ẹgbẹ Dẹmọ nṣe alakoso rẹ ni pe ki awọn ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ N. N. D. P. le mọ gẹgẹbi awọn ṣe lagbara to lasiko Idibo si ile Igbimo Aṣofin li apapọ Ijọba ilẹ Naijiria ati lati le mọ gẹgẹbi nwọn en a ipinlẹ na ṣe wa lẹhin wa.

Oniwe irohin wa fi ye wa pe irohin na ti on gbọ lati ọwọ awọn ẹgbẹ na tun fi ye wa pe awọn ẹgbẹ Dẹmọ tun ṣe alaye pe ti awọn ba le bori ibo si awọn ile igbimo Ijọba ibilẹ ni ipin Iwọ Orun nwọn yio si mọ gẹgẹbi nwọn ṣe mura ti idibo si ile igb imọ asofin ti apapọ Ijọba ibilẹ Naijiria ati lasiko idibo si ile igb mọ asofin ti ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria eyi ti idibo rẹ yio wa ye lọdun to nbọ

Oniwe irohin wa tu fi ye wa pe irohin na lati ọwọ ọmọ ẹgbe Dẹmọ tun fi han gban gba pe awọn ẹgbẹ Dẹmọ ti nṣe akoso Ijọba ipinlẹ Iwọ Orun si nṣe eyi lati le mọ gẹgebi awọn enia ipinlẹ na ti ni igbẹkẹle ninu akoso Ijọba wọn.

Irohin lati ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ ti ọwọ oniwe Irohin ni Ibadan tun fi ye wa pe ti awọn ẹgbẹ Dẹmọ ba le bori bo si awọn ile igbimọ ti Ijọba Ibilẹ ni Ipinlẹ na pe o ti da wọn loju gban-gba pe awọn aṣoju wọn ni awọn ile Igbi-mọ Ijọba Ibilẹ ti Ipin-lẹ Iwọ Orun Naijiria yio tun le mu ki awọn enia Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria le dibo fun awọn ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ to ba ti di aseko idibo si ile Igbimọ Asofin ti Apapọ Ijọba Naijiria eyiti nwọn yio ṣe idi-bo rẹ larin ọdun yi ati idibo si ile Igbimọ Aṣofin ti Ijọba Ipinle Iwọ Orun Naijiria ati pe awọn ọmọ ile Igbi-mọ Ijọba Ibilẹ jake ja-do Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria le wa gẹgẹbi ẹniti yio wa gẹgẹbi oluranlọwọ awọn ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ lasekọ idi-bo na.

Oniwe irohin wa tun fi ye wa pe ile iṣẹ Alakoso eto Ijọba ibilẹ ni ibilẹ ni ipin-lẹ Iwọ orun Naijiria ti nfi iwe ranṣẹ si awọn ile igbimọ Ijọba ibilẹ jake-jabọ ipinlẹ Iwọ orun lati le ma fi ye awọn ọmọ ile igbimọ Ijọba ibilẹ na pe asiko adehun ti ile igbimọ Ijọba ibilẹ na si ti to ati pe ki awọn ọmọ ile igbimọ na si lọ ma mu ra silẹ lati tu awọn ile igbimọ Ijọba ibilẹ na ka.



Oloye Fani Kayọde

Irohin na tun fi ye wa pe ninu awọn iwe ti nwọn fi ranṣẹ si awọn ile igbimọ ijọba ibilẹ to jade lati ile iṣẹ Alakoso Ijọba ibilẹ ti Ijọba Iwọ Orun Naijiria ni a tun ti gbọ pe nwọn fi ye awọn ọmọ ile igbimọ jọba ibilẹ na pe ti edeaiyede ba le ṣẹlẹ larin awọn ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ nṣe akoso Ijọba ibilẹ na ti nwọn yio tun ile igbimọ Ijọba ibilẹ na ka ati pe nwọn yio yan awọn igbimọ Afun shọ eyiti yio ma ṣe eto akoso Ijọba ibilẹ na ti nwọn ba le gbe edeaiyede si-lẹ lori eniti yio gbe apoti idibo silẹ lasẹko idibo fun awọn ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ (N N D P)

Larin bi ọjọ mẹsan schin ni Alakoṣo eto Ijọba Ibilẹ ti Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Niji-

Wo Oju Ewe Kẹfa

# AYUNỌRUNBỌ ATI PANPALASO (Apa Kẹfa)

## Lati Ọwọ J. O. Shoyinka

Ẹ dẹja ẹfẹ wadi Ọlọrun ti o da nyin. Njẹ ẹ ha mọ daju pe, ẹniti o ba fi idan ari idan? Ioni ni ngo gba ẹmi yin lọwọ yin, ẹ o fi dẹni ọrun alakeji aremabọ, aburo mi ti se eto fun nyin, ise to ku ni mo wo se yi, apejuwe iku ko pọ, o ri kuta bi egbere lasan ni, Ogbe kumọ le wọn ni atari osi pa wọn bamubamu.

Ki a mọ sa ti iku ti na wọn ni ọgọ re ni ẹmi wọn ti bọ, lojiji ni nwọn yo si ẹnu bode Ọrun. Ayọrunbọ si ti wa pade wọn nibẹ, bi nwọn ti nwo koo ko ni Ayunọrunbọ yọ si wọn fusa oni ẹ ma tẹ le nwọn si ntẹ le.

Wọn ko iti rin ju ẹsẹ mejila lo ti ofi da wọn duro oni ohun kan ti mo fẹ ba yin sọ, "Ese ara yin lọkan, ki ẹ ma dajuda ju pe ẹ ti di ẹbọra ohunkohun ti o ba si de ba yin ẹ gba pe kadara yin ni. Ilẹkun nla ti o nbẹ li ọkan ni, Bode Ọrun ni.

Lati igbati mo ti nba itan mi bọ, nko sọ orukọ awọn ọre Ayunọrunbọ — Orukọ ekini ẹmẹ jẹ Sakulake (Ar kutaku, Ọgbẹni wọ gbogbo wọn ti o laiye bi kiriun, Ayunọrunbọ ni ngo kan lẹkan nisiyi, oni bode yio yọju si nyin, ohunkohun ta bẹ bi ere lọwọ yin o da lohun, ẹ mase bẹru nko le kọ yin li ohun ti ẹ ma sọsa o

### SAKULAKE BẸRẸ SI SỌRỌ

Ose pupọ Ayunọrunbọ osi ku wahala wa, aki bọ sinu ẹmitutu tan, Ki a si tun bẹru eye - ẹru ẹnikẹni ko ba wa mọ, ati ti Oluwa Ẹleda Bi Onibode ba bere ọrọ lọwọ wa ao da lohun, yio si gbadun wa, Ayunọrunbọ dagbere fuu wọn, o si lọ, Sakulake kan ilẹkun, onibode si si Nwọn wọle-Onibode se ilẹkun, oro gba a Onibode Bẹrẹ si Bere ọrọ lọwọ wọn.

Ibere kini:- Kini ẹ wa de ihin?

Ibere keji:- Nibo ni ẹ ti nbọ, nibo ri ẹ nlọ?

Ibere kẹta:- iru ẹsin wo ni ẹ nsin ni bi ti ẹ ti wa

Ibere kẹrin:- Njẹ ẹ mọ ibi ti ẹ wa yi?

Ibere Karun: Bawo ni Ayunọrunbọ ti jẹ si yin

Nwọn bẹrẹ si wo ara wọn loju Onibode jagbe mọ wọn o ni ẹ da mi lohun asiko lọ awọn yo ku dagba lasan ni, ṣugbọn wọn ko lọgbọn to Ogiriwo.

### OGIRIWO DAHUN AWỌN IBERE ONIBODE

Ogiriwo ni Onibode, gbogbo wa ko le ma dahun lọkọkan ki a ma ba gba ọ lasiko, ṣugbọn bi o ba gba mi laye, ngo dahun awọn ibere re, Onibode ni, o ku ọmọ mi nso nilẹ

Idahun kini:- Ayunọrunbọ ni a tẹle dehin.

Idahun keji:- Anti ajule aiye bọ, asi nlọ si ikọle Ọrun.

Ibere keta:- Sakulake s i n Sango Ajale iji ab hun tẹ ni rere, Arikutaku nsin esu lala akiri oko abẹru wa, ọrun ba o ri da.

Oni sokoto penpe ti ṣonu bode Ọlọrun, o ba elẹkun suukun kẹru a ẹlẹkun ẹlẹkun suukun lalu okiri oko nsun ẹjẹ, Ogbori ajabalebu ninu egun Lakaiye onimọlẹ onile kengun kengun ọrun, Olomi nilẹ fẹjẹ we, Akinla.

Wọn nsin Anabi Muhammad (Salalale ewa Salamọ) Emi papa nsin Jesu Kristi ọmọ Ọlọrun

Bi oti ndahun ibere yi ni Onibode nkọ silẹ,

Idahun kẹrin;- Ẹnu Bode Ọrun ni.

Idahun karun:- Ọba ti ojẹ fun wa ni ile aiye awa papa si j emẹwa.

Nigbati Onibode kọ idahun wọn silẹ tan, o fun wọn ni iwe ẹri kọkan lati le fi kọja si Ọrun gan an. Ohun ti okọ sinu iwe ẹri wọn ni pe, ati wadi wọn de Okokoro, a si fun wọn ni iwe ẹri yi lati le kọja si Ọrun Emi ni Onibode,

O juwe ọna fun wọn, nwọn si tẹle ibẹ, nwọn nlọ rangbanja, osi kilọ fun wọn pe, ki nwọn fi iwe ẹri yi pamọ dada, ki nwọn ma si ṣe fi fun ẹnikan yẹwo

wọn o fi de bode keji.

### EṢU PARADA O YỌ SI WỌN

Bi nwọn ti n ọ ṣeṣaṣa ni eṣu pade wọn, o ni alafia fun nyin nwọn ko da lohun o tun ki nwọn lẹkeji, nwọn b ju wẹhin, nwọn wa rope Ọmọbinrin arẹwa kan ni, ara fu Ogiriwo oni ẹ ma da lohun, ejẹ ki a ma lọ, ohun ti onse lukuluku wa ki iṣe ti obinrin nisisiyi.

Sakulake ni ọmọ yio ku lọmo ti yio ye, dandan, a nilati ki ọlọmọ ku ewu, ẹ jẹki a gbọ ohun ti yio wi

Angeli pee ko da lohun ose bi esu ni

Angeli pe Ogiriwo ko da lohun sugbọn Angeli na rin sunmọ o bẹrẹsi yi pada aso rẹ di funfun lau iyẹ ni ofi se apa logan ogiriwo wọle o si yin Oluwa logo

Angeli na ni mase bẹru ẹmi ni iranṣẹ Ọlọrun Oga ogo nko wa lati pa ọ lara wọn ran mi si ọ lati wa fi ọran han ọ ni dupẹ lọwọ ori rẹ ati Ọlọrun pe iwọ ko gba ẹ tan esu iba se pe ogbo ni baba nla iya ko ba jẹ ọ ni Ọrun Apadi mu lọ tarata ti o ba de idi ilẹkun nla ni, on bode yio si ṣi fun ọ bayi Angeli yi sise fo lọ titi ofi parẹ mọ loju

### OGIRIWO KANLẸKUN ỌRUN

Nigbati Ogiriwo kanlẹkun, Onibode ṣi ilẹkun piri Oni alafia fun o, "Iwọ arakunrin mi, Onibode ni ki o wọle, nigbati o wọle tan o gbe oga na kan fun, aga yi dara ju ti Ọba lọ, iṣe ni aga yi bẹrẹ si sọ Ogiriwo soke nigbati ojoko le. obẹrẹ si wo su u.

itẹlọrun wa fun un Onibode ni jọwọ mo bẹ ẹ ara kunrin mi ẹwọn inu mi yio dun ti r o bale ma dahun awọn ibere yi ni kia kia nito pe awọn to nwọ ajule Ọrun ko ni ye lojọ oni bi oba ṣeju pe igba enia yio bi ọ nihin

Ibere Kini:- Ọdun melo ni o ṣe ni ilẹ aiye

Ibere Keji Iwọ gbaẹ mi ri?

Ibere Kẹta:- Kini o wa dehin.

Ẹo ma ka Iyoku lọ lọla.


MODUPE PRINTING PRESS

LEADERS IN MODERN PRINTING
Firms Patroise MODUPE PRESS
Becuase Of Their;—

MODERATE CHARGES
EFFICIENCY
GOOD PRINTING
IMPERISHABLE RECORD
DELIGENT SERVICES
ACCELERATIVE METHOD PRINTING

For Your Next Printing Jobs —
Just Call 21985 - Leave the rest to Modupe
We Guarantee Neat Work And Quick Service

Modupẹ Printing Press

16 Bamgbose Street
Phone 21985, Lagos

# IWE SI OLOTU

## Ẹ Ye Kigbe Awolowo Mọ

Mba dupẹ bi Alaeba ba le fun mi laye diẹ ninu Iwe Irohin Imọlẹ rẹ oloyin mọmọ lati ba gbogbo awọn ojulowo ọmọ Yoruba ati awọn enia ti o ni ifẹ si Oloye Ọbafẹmi A w o l ọ w ọ sọrọ nipa pe ki nwọn o ye ma kigbe Awolọwọ kiri mọ

Ojoojumọ ni a ma gbọ pe nwọn fi Awolowo silẹ ni gbogbo ilu yio si ma pariwo rẹ, Laipẹ yi ko to di pe nwon dajo rẹ loru ni a dede gbọ ariwo Awoo! Awo! ti gbogbo ilu si taji pẹlu irohin iro pe nwọn ti jọ Awo silẹ, ati pe nwọn ti gbe lọ si ilu rẹ (Ikenne) loju temi o da bi ẹni pe a tun nda si Oloye wa lọrun ni



Oloye Awolọwọ

Ti a ba mọ pe a nfẹ tirẹ ohun ti oyẹ ki a ṣe ni lati ma gbadura fun lojojumọ nigbati a ba kirun tabi ni ṣooṣi pe ki Ọlọrun fun i ẹmi gigun ati alafia ko lede ba wa layọ ki ẹ si jẹki a s o w ọ p ọ lati dibo fun nigbakigba ti ibo ba de. Nitorina mo bẹ yin ẹ ye pariwo rẹ mọ, ariwo ti a npa yin tubọ da si lọrun ni o. Ẹ jẹki a sinmi ariwo rẹ ki a duro de ibo lati di fun un. Awo yio de ba wa layọ.

Emi ni
Mọshudi Ademosu
Alias Thurder Bow
EKO

Nwọn tun fẹ ta awon Yoruba fun awon hausa. Lati igbati won ti gba Oloye Akintola si ipo olotu gbogbo nkan tun bere si baje lọ siwaju si i.

Odi pe ki awon oṣelu ma gbe moto kakiri lati fi ṣe janba fun awọn alatako wọn nitori aise ti nwọn eyi ko ye mi o. rọ omo fẹ ki enyin ọmọ Ijẹbu-rẹmọ ati awọn ilu ivoku ti o wa ni Ijebu ro eyi wo lati dibo fun ẹgbẹ Ọlọpẹ nigbati ibo ba de ki nwon ba le tun pa qa si ijoba ti Akintola fi eru gba

Mo ki awọn ọmọ Isara fun akinkaju nwọn ti nwọn o si jẹki ẹgbẹ Dọmọnu ko fi nwọn sinu okunkun. Ki Ọlọrun ma jẹki a dọmọ wa nu o Amin.

Laipẹ yi, ni agbara Ọlọrun gbogbo nkan fun gbẹ ọlọpẹ ti oloye Ọbafẹmi Awolọwọ Baba ni Ikẹnnẹ nṣe olori rẹ. Mo tun bẹ yin gidigidi e ma jẹki awọn omo ẹgbẹ Dẹmo tan yin jẹ pẹlu ogbon arekereke awọn ọpẹ kete ndagbasino Adamọ nbajẹẸgbẹ. Ọlọpẹ goke a g b a si inu nbi ẹgbẹ Dọmọnu Oke lẹgbẹ Awolọwọ yio ma lọ o ani o di gba o

Mo dupẹ pupọ lọwọ Olotu ati awọn isagbe rẹ ọkọ ọba ko ni ṣa nyin lẹṣẹ o

Emi ni,
Samuel Adenupẹ
Eko

## Anfẹ Ina Lentiriki Ni ilu Idofia

Olotu jowo gbami laye ninu Irohin imọlẹ ti nfi ododo han yato si irọ lati kesi ijọba ipinlẹ ariwa lati fun wa ni ina lẹntiriki ni ilu-wa idọnfian

Inu awa ọmọ ilu idofian ati gbo gbo olugbe ilu idọfia yio dun bi ijọba ipinlẹ Ariwa Naijiria ba le fun wa ni ina mọnamọna lẹntiriki ni ilu idofia nitori wipe ojẹ abuku fun ilu idọfia nipa aiko si ina lẹntiriki ni ilu na Nitoripe ile iwasan to wa ni ilu na ko ni ina bẹsini post office ilu idofian koni eleyi si tun jẹ abuku popọ wpe ile ile igbimọ idọfin ilu na ko ni ina Nipa bayi mobẹ ẹnyin ile isẹ ijọba ipinlẹ Ariwa ati papa alaṣẹ ina ilẹntiriki fun ijọba apa ọ Alhaji Yusuf Maitamasule ati olotu ipinlẹ ariwa Alhaji Ahamodn Bello lati lo ipo rẹ rere lati fun ilu Idofian ni Ina lẹntiriki eyiti o jẹ ẹkan fun wa ni ilu Idọfian kokere rara ninu ilu towa ni ilẹ Ilọrin ko fi owo or! jafara ara ni i u Idọfia o yẹ ki awa ni ipin ninu eto idagbasoke ọlọdun mẹfa ti Ijọba apapọ gbe kalẹ ejọwọ ẹba wa moju o ọrọ na kẹsiri wipe awa na jẹ anfani to tọ siwa Olotu Modupẹ aye ti ẹgba mi

Emi ni
Alfa M. Arikeṣọla
IDỌFIAN-ILỌRIN

## Awa Ọmọ Ijẹbu Ko Faramo Ẹgbẹ Dẹmọnu

OLOTU Jọwọ gba mi laye ninu iwe Irohin Imọlẹ oloyin mọmọ ti oma njade lojojumọ lati ke si awọn ọmọ Isara ati gbogbo awọn ilu to wa ni Ijẹbu.

Nisisiyi gbogbo wa lo nri bi Ijọba ẹgbẹ Dẹmọnu ti Akintọla nse Olori re se nfi iya jẹ awon omo ẹgbẹ ọlọpẹ ati ẹgbẹ Alakuko. Nwon nse gbogbo eyi ki wọn ba le fi agbara tun ṣe Ijọba Iwọorun ti wọn mọ pe yio bo lowo won laipẹ yi lagbara Ọlọrun'


MAFI OWO RẸ ṢE "OFO" MỌ NIPA RIRA AWỌN RỌBIRỌBI TONIKI NITORIPE OWO WỌN RỌJU ARA RẸ LO NṢE IYẸN D JU O BẸRẸ OJULOWO HAUNHAUN AYONRAN TONIKI TI WỌN NPE NI

"MINOPHOS—TONIKI"

Aworan ẹgbẹ yi fi han ọ gbangba bi ẹda eni ti ri laisi "ẸRAN ARA" etipe ojulowo toniki to le ṣe iṣẹ ribiribi ni ẹjẹ ara, iṣọri ara ninu egungun gẹgẹbi awọran yi to fi han ọ, MINOPHOS Toniki a ma ejẹ fa ti tun si ara, papa ti e ia ba nru si ogurodo tabi f in wa hala iṣẹ ṣiṣe aiko nri orun sun daradara to, beni o si darajulọ pẹlu bi ara enia ba n bcna nigbakugba tabi lehin aisan tabi amodi bi igbona, iba pọnjupọnju tabi a a wiwo enia nigbaku gba,




Ati fun iṣọn a lokunfati egungun ara ti o ba dabi ẹnipe omurọ tabi ti ko la gbara to. Ṣ dan igo kan egbogi tọniki yi wo iwọ yio si ma rohin rẹ fun gbogbo enia pẹlu. Bere ni Ṣọbu awọn:–

NIGERIAN MEDICINE STORES
4 Tinubu Square, Lagos

WATERLOO (SHOP) MEDICINE STORES
8, PALMCHUCH STREET LAGOS
P, O, BOX 333



HELLO ! HELLO !! HELLO !!!

OLUSHI SOCIALISTS

PRESENTS

FIRST ANNIVERSARY DANCE

at Foresters Centenary Hall
22, Odunlami Street Lagos

ON FRIDAY, 21st A UGUST, 1964, AT 6 p, m. till dawn

MUSIC BY

New Time Enterprises
Bashy & His Young Stars Orchestra

Ladies and Gents, dont be told of what happen at Foresters on that 21st August 1964, how Bashy will give you many latest hits and how New Time will give you many hits of Roy Chicago, Eddie Okonta, I. K. Dairo & Broadway Dance Band Arom Ghana Bashy is asuring you to bring along your Termogene or Mentholatum to rub your body after closing.

COME THERE IN TIME TO AVOID RUSHING

Bar Bar Inexhaustible

Tickets 3s Flat

Tickets obtainable at 16, Bamgbose Street Lago (Irohmole Office) and at 3, Olushi Street Lagos

# Ekunrẹrẹ Idajọ Oloye Awolọwọ (Apa 13)

Adajọ tun ba ọrọ rẹ lọ bayi pe: ti on ba ju awọn enia yoku se..ọn ti on si fi Oloye Awolọwọ silẹ ati pe awọn enia yoku si jẹ irinṣẹ fun Oloye Awolọwọ ati pe ti on ba si fi Oloye Awolọwọ sile lati jiya ohun to ṣe pe ki iṣẹ ohun to tọna ki on jẹki awọn yoku jiya na ko ofin mun rara ati pe eleyi jẹ ohun t ohun ti ile .jọ on da ati pe ki ise agbara on rara,

Adajọ na sọ pe: to ba jẹ pe Oloye Awolọwọ nikan ni o ni on ba fi silẹ ki osi ma lọ pẹlu itiju ara rẹ ati pe eleyi si jẹ ohun to jẹ ẹṣẹ oṣelu. Adajọ na tun nkan ẹnurin wa ti enia ko mọ rara ati pe ohun ti mo mọ ni nkan to wa ni waju mi yi ati pe ohun ti mo fi sọ pe aif.ran ara yin si ti jinlẹ pupọ j ati pe ki iṣe isẹ adajọ lati lọwọ ninu ij. ọrọ oselu fun ohunkohun to le bẹ silẹ.

Adajọ ile ẹjọ na tun sọ pe Oloye Aw.lọwọ sọ pe ẹjọ na pẹ pupọ ki on to da ati pe ko pẹ rara ọgbẹni S.wẹmimọ sọ pe to ba jẹ Oloye Awolọwọ lo wa ninu ipo ti on wa yi, yio mọ iru iṣẹ ti on se ati pe gbogbo ọrọ ti nwọn sọ ni ile ẹjọ na to ẹgbẹrin .we ati awọn ẹsun ti nwọn si tun ro silẹ si tun to bi ẹgbẹta ewe. Ọgbẹni Sowẹmimọ tuu sọ pe inu on dun lati sọ pe gbogbo ẹjọ na ti pari ati pe ko jẹ ẹdun ọkan mi lati sọ pe mo da enia l'ẹbi laijẹ pe ki nsọ pe ojare su.bọn gbogbo ọrọ na ko gba ọna tẹ lọ rara ti pe mi ko le ro nkan to sẹlẹ nibi kan bi k. se awọn ọrọ to jẹmọ nkan na.

Ọgbẹni Sowẹmimọ tun sọ pe on ko ri si lati mọ iru ẹwọn ti nwọn ba lẹ gbe ọ s i. Ṣugbọn m o ri pe gbogbo nkan na pe ọ w ọ rẹ lo ti wa Ko si nkan ti mo le se mo si mọ gẹgẹbi ero ọkan rẹ tiri ati be o si nsọ ọrọ nkan to tun j. pe o ti ga ju ẹ pupọ ati papa fun ori ilẹ ede patapata po ati pe eleyi n i nkan Ai mọ si fara mọ pupọ ju

Ọgbẹni Ṣowẹmimọ t u n sọ pe, uni lati mọ gẹgẹbi on ti rin s u n mọ Oloye Awolọwọ nigbati on si a gẹgẹbi adajọ kekere ni ilu Ijẹbu-Ode ati pe oju mi lọ nipa ọna ofin papa o tun jẹ oluko fun m i nigbati mo wa ni ile ẹkọ

Ọ.bẹni Ṣowẹmimọ tu nsọ pe nigbati on wa nipo adajọ bayi pe on k o mọ pe iru bi Oloye Awolọwọ to ti jẹ Olori Alakoso Ijọba tẹlẹ ni wọn yio m wa siwaju on lati ṣẹjọ tun. Ṣugbọn nkan ti mo ni lati ṣe ni ati pe ohun to ba ẹjọ to wa ni waju on lọ ni.

Lẹhin eyi ni adajọ na ko awọn nkan sinu iwe idajọ rẹ nigbati o to ti nkan bi iṣẹju diẹ o si . be ori soke ni o ba sọ gẹgẹbi oye ẹwọn ti wọn yio lọ

Ọgbẹni Ṣ wẹmimọ wa sọ lẹhin eyi pe gẹgẹbi on ti sọ tẹlẹ, o ni Oloye Awolọwọ jẹbi ẹsun na ni ẹsun ekini ẹwọn ọdun mẹwa ẹsun keji ẹwọn ọdun marun ẹsun kẹta ẹwọn ọdun meji ati pe yio lo ẹwọn na ni alopọ

Ninu aw. n ti adajọ na ju s'ẹwọn pẹlu oloye Awolọwọ ni awọn enia mẹtadinlogun awọn ni



Oloye Awolọwọ

Michael Omishade ọkan ninu awọn agbẹjọro ni ile Naijiria ati ọmọ ẹgbẹ Afẹni fẹre ni ile igbimọ Asofin apapọ ijọba Naijiria Adajọ si sọ fun pe; o si da on loju nipa ẹsun ti awọn fi kan ati pe ot tọ ni gbogbo ọrọ ti agbẹjoro fun ..ba nipa ẹsun ti o fi kan Adajọ si sọ pe Omishade yio lọ si ẹwọn Ọdun meje fun ẹsun ekini Ọdun mẹta fun ẹsun kej Ọdun meji fun ẹsun kẹta ati pe yio lo gbogbo rẹ pọ

Omishade si fesi bayi pe Oluwa mi mo si wa lori pe emi ko dẹsẹ, sugbọn adajọ si dahun pe ẹjọ rẹ si jẹ ohun to buru ati pe on si pe on lo lẹnu pupọ ati pe on ko mọ ohunti o su. ọ siru nkan bẹ Adajọ si pe iwọ ọdọ ara rẹ to ṣẹṣẹ bẹrẹ igbesi aiye rẹ Adajọ sọ pe ti ero rẹ ba yori o rere pe ko ni si agbẹjọri kankan ati pe nse io yẹ ki on fi iya to pọ jẹ ki o le jẹ ari kọgbọn fun fun awọn enia miran Adajọ sọ pe

WO OJU EWE KẸFA

BI O BA NI
1we—Titẹ
FUN
Lilo nibi Iṣẹ rẹ tabi orişirişi
Iwe itufọ tabi ijade Oku
ATI
Iwe Igbeyawo
KỌWE SI ILE—IṢẸ—ẸRỌ ITẸ IWE
Modupẹ Printing Press
16, Bamgboṣe Street, P. O. Box 1495
Telephone: 21985, Lagos.
EKETE NI ẸRỌ ITẸWE WA NHAN
OWO PỌỌKU NI A SI NGBA
IROHIN KO TOAFOJUB
Dan wa wo lẹkan soso ṣoṣo ko si ri iyatọ

GBOGBO ARA ILU NKỌ ORIN IYIN ati AYỌ NIPA "DYNAMIREN" TỌNIKI



ALE-BI-ELE Egbogi Tọniki Jamọnu titun ti gbogbo ... a Ilu Eko ati jakejado Naijiria mọ daju fun Akọ .gbara ati Ajẹbidan iṣẹ Rẹ lara Agbalagba Ọkunrin g.ogbo.

Bi arẹ ara ba nmu ọ, nigbakugba fun wahala lala şişẹşẹ ti o kọ ie jẹun daradara, tabi ki o male sun dada ọkun lọsan tabi loru tabi awọn iṣan ara rẹ gbogbo ki şe fun daradara ti Eemi (Breath) inu ko ba gunlẹ daradara wọn iṣẹ tabi wahala şişe tabi fun awọn ailera gbogbo 'nyin ti ọjọ ori rẹ (age) ba ti kọja Ọgbọn ọdun o si de adọrin tabi jubẹ lọ. Mo dupẹ "DYNAMIREN' ni egbogi ti o nfẹ lati sọ ara di ọtun patapata anu rẹ a si jọlọ, ẹran ara rẹ ti o ti hunjọ yio bi ẹ s'i do dada. Ara rẹ yio ma gbe kankan nigbakugba y'Arẹ" n gbakugba yio salọ pẹlu igoọaba-dun ati alafi diro de ọ. Iyẹn daju. Bere Egbogi na ni Ṣọbu: awọn

NIGERIAN- MEDICINE STORE
4, Tinubu Square Lagos

Waterloo Medicine Stores
8, Palmchurch Street, Lagos.
hone: 22878 Nigeria, (Ọja Ita Faji)
ATI NI AWỌN ṢỌBU
IṢẸ OLODUMARE DISPENSARY
IBADAN

IROHIN IMOLE

IMOLE ORẸ AIYE. TENI GBOGBO LAWA

No. 763. THURSDAY, AUGUST 6 1964 (2D)

## Ẹgbẹ Ọdọ Ọmọ Ogun Awo Fẹ Ṣe Ipade

EKO:- Ni ọjọ Ru ti iṣe Ọjọ k run oṣu yi ni Irohin de ọwọ wa lati ọwọ Ọgbẹni Samson Ade Sowẹmmọ ọkan ninu awọn igbimọ ẹgbẹ Awo National Brigade ati akọwe Alakoso ẹgbẹ Afẹnifẹre fi ye wa pe awọn ẹgbẹ odo ti ẹgbẹ Afẹnifẹre jake jado ilẹ Naijiria yio ṣe ipade kan ni ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kẹjọ oṣu yi

Ọgbẹni Ṣowẹmimọ sọ pe awon ẹgbẹ Ọdọ ti yio papọ ṣe ipade nla ni ọjọ na ni ẹgbẹ Awo National Brigade, Awo National Vanguard ati ẹgbẹ odo kan ti njẹ Awo Pioneers, Ọgbẹni Ṣowẹmimọ fi ye oniwe wa pẹ ni ile Iṣẹ ẹgbẹ Afẹnifẹre ti Oke do Ibadan ni nwọn yio ti ṣe ipade na.

Ọgbẹni Sowẹmimọ tun ṣọ siwaju si pe gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ na jakejado lẹ Naijiria ni yio wa sibi ipade na Ọgbẹni Sowẹmimo tun fi ye Oniwe Irohin wa pe ẹniti yio wa gẹgẹbi alaga ipade ojo na Alhaji Busari Obiṣẹṣan olori ẹgbẹ Afẹnifẹre ni ilu Ibadan.

Ọpọlopo awon olori ẹgbẹ Afẹnifẹre ni yio wa sibi ipade na lati wab awọn ẹgbẹ oda na soro Ninu awon olori odo ẹgbẹ na ti yio wa sibi ipade na ni Ọgbẹni Ojetunde tio jẹ alaga ẹgbẹ na lati Eko ati Ọgbẹni Ogunpola.

Ọgbẹni Sowẹmimo so ni ipari oro rẹ pe opolo awon olori ẹgbẹ Afenifẹre ni lati ilẹ Naijirja ni yio tun wa sibi pade na.

# Oloye Johnson Ko Ni Gbe Apoti Ibo Silẹ L'ọdun Yi Bi?

APAPA:— Ni ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kẹrin oṣu yi ni Alakoso eto iṣẹ fun Apapọ Ijọba Naijiria Oloye Joseph Modupẹ Johnson ba awọn oniwe irohin nsọro ni ebute ọkọ oju omi ni Apapa nigbati o fẹ lọ si irin ajo rẹ lọ si ilu Oyinbo fun isimi oṣu meji ti Oloye Johnson ni lo ti ndahun ibere ti awọn oniwe irohin nbere lọwọ rẹ pe boya yio gbe apoti ibo silẹ laseko idibo si ile Igbimọ Aṣofin ti Apapọ Ijọba Naijiria.

Oloye Johnson si tun sọ nigbati o fẹ wo ọkọ oju oni to fẹ gbe lọ si ilu oyinbo lati lọ lo isimi rẹ ni Oloye J. M, Johnson ti sọ pe ki iṣe ero on nida lati gbe apo ti ibo si e lo jẹ ohun kan to je pataki bi ko ṣe pe lati ri pe on dad.. ninu ẹgbẹ on N, C. N. C,

Nigbati oloye J, M, Johnson tun rdahun si ibere miran ti awọn oniwe Irohin tun bere lọwọ oloye Johnson ni o ti sọ pe ki iṣe nkan to lọ titi fun on lati sọ pe on ko ni gbe apoti sile laseko idibo si ile igbimọ asofin ti apapọ Ijọba ile Naijiria

Nigbati awọn oniwe irohin tun bere lọwo Oloye Jonson lori ẹkunwo owo-oṣu eyiti oluwadi Morgan ṣe lati fi kun owo oṣu awọn oṣiṣẹ ilẹ Naijiria ati lati gba owo ọya oṣu mẹfa ?

Oloye J. M. Johnson si da lohun pe ohun to jẹ pe Ijọba apapọ ilẹ Naijiria



J. M Johnson

ri pe awon ile iṣẹ miran ti ki iṣe ti Ijọba ilẹ Naijiria ni lati ri mọ pe awọn san ẹkunwo owo-oṣu na fun awọn oṣiṣẹ wọn ati pe o si ti ṣe ohun ti nwọn ti ba awọn olori oṣiṣẹ ati awọn Alakoso eto i e iṣẹ gbogbo ṣe adehun lati san ẹkunwo owo—oṣu eyiti igbimọ oluwadi Morgan ṣe

Oloye Johnson tun fi ye awọn oniwe irohin pe ko si ọna ti awọn Alakoso ile ti ko ti san owo na fun awọn oṣiṣẹ wọn le gbe e gba laje pe nwọn san owo ati pe ohun to jẹ pe nwọn ti o ṣe adehun pe lori ni lati san fun awọn osiṣe na oloye Johnson si tun ṣọpe Alakoṣo ile iṣẹ to ba kuna lat san ẹkunwo owo oṣu na fun awọn oṣiṣẹ wọn pe Ijọba apapọ ni lati ripe awọn bawọn faọrọnani

Oloye Jonhson sọpe apapọ Ijọba ile Nijiria ti se ta lati mu ileri wọn ṣẹ ati lali ripe gbogbo adehun ti wọn ba awọn olori awọn oṣiṣẹ ṣe ni nwọn yiosi mu ṣe patapata jake-jado ilẹ Naijiria

Oloye Johnson tun fi ye awọn oniwe irohin pe nkan ti o yẹki on lọ fun isimi oni on l.o ọrọ sẹnu awọn ẹgi losija atipe bi nkan bi osu meje loti jeki on ṣimi oloye Johnson ofin Dokita ni on koleyi nipa ti isimi na

LATI OJU EWE KINI

ria ti oloye Rẹmi Fani Kayode si ti bẹre ni tu ọpọ lọ awọn ile igbimọ Ijọba Ilẹ ka ninu awọn ile igbimọ Ijọba ibilẹ ti nwọn tuka na ni ile igbimọ Ijọba ibilẹ meji ni ẹkun Oshun awọn ni Ogbomoshọ ati irẹpọdun awọn mẹta miran t wọn tun tuka na Ijẹbu ati i e igbimọ meji ni ẹkun Ẹgba.

## Akiyesi Pataki

Si Gbogbo Ẹnyin Onkawe Irohin Imọlẹ Abẹokuta ati agbegbe rẹ Ti o ba fẹ ra Irohin Imọlẹ ti o njade ni Ojojumọ lọ ra lọwọ Aṣoju wa Omidan Owokọya.

Owo Bookshop
Ṣbapọn gọ - Oko Road
ABẸOKUTA

Ti Eni ẹn ni Irohin Imọlẹ kọbọ meji pere sini.

LATI OJU EWE KARUN

nitorina pe on yio kọ ẹnu rẹ silẹ ki ohun ari ssni ile ẹjọ ati pe yio s jẹ ọ ohun iranlọwọ.

Gabby Shaṣọrẹ ti o jẹ oniṣ ro owo adajọ si ju si ẹwọn ọdun marun. Ile ẹjọ si ri pe o jẹbi lori ẹsun mẹtẹta na.

Gabby Shaṣorẹ fi ye ile ẹjọ pe on mọ pe on wa gẹgẹ bi alai dẹṣẹ Adajọ ile ẹjọ na si d hun pe ẹjọ ti nwọn ro mọ Shaṣọrẹ lẹsẹ si ti pọ ju Adajọ tun lẹnu kan pe o lọ fun ẹkọ ni ilu Ghana ilẹ meji ni ẹsun ekin ẹwọn ọdun marun, ẹsun keji jẹ ọdun mẹta ati ẹsun kẹta ọdun meji gbogbo ọdun ẹwọn na ni yio lọ pọ.

Adeyin Akinsanya ọkan ninu awọn agbẹjọrọ ti ilẹ Naijiria ni adajọ ile ẹjọ na tun ju si ẹwọn ọdun mẹta ṣugbọn Adeyiga sọ pe on mọ pe on ko dẹṣẹ Adajọ si sọ pe o da on loju pe Adeyiga lọ fun ẹkọ iṣẹ ogun ni Ghana pẹlu awọn yoku lati le doju Ijọba apapọ delẹ, Adajọ si ni o jẹbi lori ẹsun ekini ati ekeji ṣugbọn ko jẹbi lori ẹsun kẹta

Sunbọ Jibowu ti o jẹ agbe ni adajọ ju si ẹwọn ọdun meji ko si jẹbi lori ẹsun ekini ati ekeji ṣugbọn o jẹbi lori ẹsun kẹta, awọn ẹkan oṣẹ ti nwọn ri lọwọ on. Adajọ bere lọwọ rẹ pe ṣe o ni nkan lati sọ. ?

Jibowu si sọ pe: Oluwa mi mo si gba pe mi ko dẹṣẹ ati pe ki o ro awọn ọjọ ti mo ti lọ l'ẹgba ẹwọn Ọgbẹni Somẹmimọ sọ pe Sunbọ jẹ ẹgbọn Ologbe Olumuyiwa Jibowu ati pe to ba wa laipe ti on ba ṣe bẹ da Sunbọ Jibowu silẹ pe Ologbe Olumuyiwa yio ba on wi.

Printed and Published by Modupẹ Printing Press 16. Bamgbose Street Lagos Phone 21985
Editor: TUNJI ADEỌSUN 45, Campbell Street Lagos 6/8/64.